# Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ sí síṣe àmúlò Èdè

## Ní Ìpínlẹ̀ New York






**Office of General Services**
**Office of Language Access**

## Òfin Ìlẹ́tọ́ sí síṣe àmúlò Èdè ti Ìpínlẹ̀ New York

Àwọn ènìyàn Ìpínlẹ̀ New York ń sọ èdè tó lé ní ẹgbẹrin (800). Láti rí i dájú pé gbogbo ènìyàn ìpínlẹ̀ New York lè ríbi lo àwọn ètò àti àǹfàní ìjọba—gbogbo bó ti le wù kí o lè sọ Gẹ̀ẹ́sì tó—Gómìnà Kathy Hochul buwọ́ lù òfin tí yóò jẹ́ kí àwọn ènìyàn lè máa jẹ àǹfàní ètò ìjọba nípa ti èdè lílò, tó sì tún ṣe ìdásílẹ̀ Ilé-Iṣẹ́ ìjọba tó ń rí sí ọ̀rọ̀ Jíjẹ àǹfàní ṣíṣe àmúlò èdè ní ìpínlẹ̀ náà. Ilé Iṣẹ́ Ìlẹ́tọ̀ sí Èdè (Office of Language Access), lábẹ́ Ilé Iṣẹ́ tó wà fún Iṣẹ́ Gbogbogbò (Office of General Services), ló wà láti rí i dájú pé àwọn àjọ ìjọba Ìpínlẹ̀ New York tí wọ́n wà lábẹ́ òfin yìí ṣe àmúṣẹ rẹ̀ bó ti tọ́ àti bó ṣe yẹ.

**Lábẹ́ òfin yìí, àwọn àjọ ìjọba Ìpínlẹ̀ New York tí wọ́n ń pèsè iṣẹ́ tàbí àǹfàní fún ìlú gbọ́dọ̀:**

1. Pèsè aṣògbufọ̀ fún ẹni tí wọ́n bá ń pèsè iṣẹ́ tàbí àǹfàní kan fún ní èdè abínibí rẹ̀, tí ó fi mọ́ Èdè Adití ti ilẹ̀ Amẹ́ríkà (American Sign Language, ASL).
2. Túmọ̀ àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tó ṣe kókó tó níi̇ṣe pẹ̀lú iṣẹ́ tàbí ẹtọ wọn sí àwọn èdè méjẹ́èjìlá (12) tí àwọn ènìyàn ìpínlẹ̀ New York tí wọn kò gbọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì dáadáa ń sọ jùlọ. Àwọn àjọ Ilé Iṣẹ́ ìjọba tún lè túmọ̀ àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wọn tó ṣe kókó sí bíi èdè mẹ́rin mîìràn ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ìlànà tó wà nínú òfin ṣíṣe àmúlò èdè yìí.
3. Yan Adarí Ètò Jíjẹ àǹfàní Lílò Èdè Abínibí (Language Access Coordinator) tí yóò ṣiṣẹ́ pẹ̀lú Ilé Iṣẹ́ Ìlẹ́tọ̀ sí Èdè abínibí láti rí i dájú pé àjọ wọn ń tẹ̀lẹ́ òfin Ìlẹ́tọ̀ ṣí èdè.
4. Gbé Ìlànà Ètò Ìlẹ́tọ̀ ṣí Èdè (Language Access Plan) wọn sí ojú òpó wẹ́ẹ̀bù àjọ wọn kí wọ́n sì máa ṣe ìmúdójú-ìwọ̀n rẹ̀ ní ọdún méjì méjì.

Ilé Iṣẹ́ Ìlẹ́tọ̀ sí Èdè abínibí yóò máa ṣe àgbéjáde ìjábọ̀ nípa àwọn iṣẹ́ wọ̀nyìí ní ọdọọdún.

Kàn sí **languageaccess.ny.gov** fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa Ilé Iṣẹ Ìlẹ́tọ̀ sí Èdè abínibí, àwọn àjọ tí wọ́n wà lábẹ́ òfin náà àti láti jábọ̀ nípa ìrírí rẹ lórí jíjẹ àwọn àǹfàní lílẹ́tọ̀ ṣí èdè.

Àwọn Mílíọ̀nù méjì àti àbọ (2.5 million) ènìyàn ní Ìpínlẹ̀ New York ni wọn kò le sọ Èdè Gẹ̀ẹ́sì dáadáa. Àwọn wọ̀nyìí ni èdè méjìlá tí wọ́n ń sọ jùlọ ní Ìpínlẹ̀ New York, yàtọ̀ sí Èdè Gẹ̀ẹ́sì:

- Èdè Lárúbáwá
- Èdè Bengali
- Èdè Chinese (tó fi mọ́ Cantonese àti Mandarin)
- Èdè Faransé
- Èdè Creole ti Haiti
- Èdè Ilẹ̀ Italy
- Èdè Ilẹ̀ Korea
- Èdè Ilẹ̀ Poland
- Èdè Ilẹ̀ Rọ́ṣíà (Russia)
- Èdè Ilẹ̀ Spain
- Èdè Urdu
- Èdè Yiddish

**Bí o ṣe lè Lo Káàdì "I Speak" (Mo Gbọ́ Èdè) Rẹ**

Pẹ̀lú ìwé ìlànà yìí, o lè gba káàdì "I Speak" (Mo Gbọ́ Èdè). O lè lò ó láti fi ṣe atọ́ka èdè tí ìwọ bá yàn láàyò. Ìwọ lè mú káàdì rẹ lọ́wọ́ kí o sì fi han òṣìṣẹ́ ní èyíkéyìí ilé iṣẹ́ ìjọba Ìpínlẹ̀ New York tó wà lábẹ́ òfin Ìlẹ́tọ̀ sí èdè yìí, nígbà tí o bá fẹ́ iṣẹ́ tàbí jẹ àǹfàní wọn. Èyí yóò ṣe ìrànwọ́ fún òṣìṣẹ́ àjọ ìjọba láti ní àgbọ́yé bí yóò ṣe wá onítunmọ̀ tó tọ́ fún ọ. O tún lè gba káàdì náà sí orí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ rẹ—kàn tẹ̀lé àwọn ìgbésẹ̀ tí ó wà ní ìsàlẹ̀ wọ̀nyìí .

**Láti gba káàdì náà sí orí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ rẹ:**

1. Ṣàyẹ̀wò kóòdù QR.
2. Yan èdè rẹ nínú àtẹ èdè náà.
3. Tẹ ààmì tó wà ní igun ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún ní òkè ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ rẹ láti fi pamọ́ sí orí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ rẹ.
4. Ṣí káàdì náà kí o sì fi han òṣìṣẹ́ ní gbogbo ìgbà tí o bá lọ ṣe àbẹ̀wò sí àjọ Ìjọba Ìpínlẹ̀ láti lè lo ètò iṣẹ́ tàbí jẹ àǹfàní wọn.

**Ǹjẹ́ ìwọ mọ̀...?**

Èdè Adití ilẹ̀ Amẹ́ríkà (American Sign Language, ASL) ni èdè àkọ́kọ́ fún ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ní orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà (United States) àti Canada. Nígbà tí ASL jẹ́ èdè adití tó jẹ́ alámúlò-jùlọ láàrin àwọn Adití àti àwọn tí wọ́n ní Ìpènijà Ọ̀rọ̀ Gbígbọ́ ní orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà (United States), èdè yìí kìí ṣe ti gbogbogbò. Orísirísìí àwọn èdè adití ni wọ́n ń lò ní àwọn agbègbè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, gẹ́gẹ́ bíi Èdè Adití ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì , Èdè Adití ilẹ̀ Faransé tàbí Èdè Adití ilẹ̀ China. Àwọn èdè adití lè ní àgbékalẹ̀ ètò tó yàtọ̀ sí àwọn èdè sísọ, alohùn lọ. Gẹ́gẹ́ bíi ẹni tó bá kọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì gẹ́gẹ́ bíi èdè kejì, àwọn tí wọ́n ń lo ASL lè ní ìṣòro lílo èdè Gẹ̀ẹ́sì fi sọ̀rọ̀ tí wọ́n yóò sì ní ẹ̀tọ́ sí áyan-ògbufọ (onítunmọ̀) nígbà tí wọ́n bá ń bèrè fún àwọn ètò tàbí àǹfàní lọ́wọ́ àwọn àjọ ìjọba Ìpínlẹ̀ New York tí wọ́n wà lábẹ́ òfin tó nílò ṣe pẹ̀lú níní àǹfàní sí lílo èdè.